Kí *Lo* Máa Ṣe tí Wọ́n Bá Ń Tojú Bọ Ọ̀rọ̀ Ẹ?



1 ÌGBÀ TÓ O DÁ WÀ

OHUN TÓ ṢẸLẸ̀ SÍ ẸNÌ KAN

"Ó kàn máa ń wù mí kí n dá wà nígbà míì, kí n máa dá ṣe nǹkan mi. Àmọ́ àwọn ẹ̀gbọ́n mi obìnrin máa ń ṣe mí bí ọmọdé, gbogbo ọ̀rọ̀ mi ni wọ́n máa ń fẹ́ mọ̀! Kì í kúkú ṣe pé mò ń fi nǹkan kan pa mọ́, kò kàn wù mí kí n bá ẹnì kankan sọ̀rọ̀ ni!" —Allison.

Kí lo rò pé ó mú kí àwọn ẹ̀gbọ́n Allison máa ṣe é bí ọmọdé?

Kí lo rò pé Allison lè ṣe kó lè jẹ́ káwọn ẹ̀gbọ́n ẹ̀ mọ̀ pé ó kàn máa ń wu òun kóun dá wà láwọn ìgbà míì ni?

Ká ní ìwọ ni Allison, kí **lo** máa ṣe?

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

2 YÀRÁ RẸ

OHUN TÓ ṢẸLẸ̀ SÍ ẸNÌ KAN

“Tí mo bá pa dà délé lọ́jọ́ kan, tínú mi ò sì dùn, ó kàn máa ń wù mí kí n dá wà. Òótọ́ ni pé ó dáa kéèyàn ní òbí tó nífẹẹ́ èèyàn, àmọ́ ní-gbà míì, wọ́n á kàn já wọ yàrá mi lásìkò tí kò wù mí kí n bá ẹnì kan-kan sọ̀rọ̀!” —Ryan.

Ṣé o rò pé ọ̀rọ̀ Ryan jẹ àwọn òbí ẹ lọ́kàn?

Tọ́rọ̀ bá rí bẹ́ẹ̀, kí lo rò pé Ryan ń ṣe (tàbí tí kò ṣe) tó ń dá kún bí ọkàn àwọn òbí ẹ ò ṣe balẹ̀?

Ká ní ìwọ ni Ryan, kí **lo** máa ṣe káwọn òbí ẹ lè fọkàn tán ẹ?

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania



3 FÓÒNÙ RẸ

OHUN TÓ ṢẸLẸ̀ SÍ ẸNÌ KAN

“Ìgbàkigbà tí mọ́mì mi bá rí fóònù mi nílẹ̀ ni wọ́n máa ń ka ọ̀rọ̀ tí mo fi ránṣẹ́ sáwọn èèyàn. Ìgbà kan tiẹ̀ wà tí wọ́n yọ nọ́ńbà ọ̀rẹ́ mi kan kúrò lórí fóònù mi torí wọ́n gbà pé kì í ṣe irú ẹni tó yẹ kí n máa bá rìn.” —Nadine.

Ṣé o rò pé ọ̀rọ̀ Nadine jẹ́ mọ́mì ẹ̀ lọ́kàn?

Tọ́rọ̀ bá rí bẹ́ẹ̀, kí lo rò pé Nadine ń ṣe (tàbí tí kò ṣe) tó ń dá kún bí ọ̀kàn mọ́mì ẹ̀ ò ṣe balẹ̀?

Ká ní ìwọ ni Nadine, kí **lo** máa ṣe kí mọ́mì ẹ lè fọ̀kàn tán ẹ?

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania